# kò lẹtọ láti ta ẹjẹ musulumi kankan silẹ ayaafi pẹlu ọkan nínú nkan mẹta

Láti ọdọ Ibnu Mas'ud kí Ọlọhun yọnu si; o s'ọpé: Òjíṣẹ́ Ọlọhun kí ikẹ àti ọla Ọlọhun máa ba a s'ọpe: «kò lẹtọ láti ta ẹjẹ musulumi kankan silẹ ayaafi pẹlu ọkan nínú nkan mẹta: Adelebọ tàbí Abilekọ l'óbìnrin tàbí l'ọkunrin tí o ba se zina, ati ẹmi kan tí o pa ẹmi keji lai l'ẹtọ, àti ẹni tí o fi ẹṣin ṣílẹ tí o si yapa kuro ninu awujọ (awọn musulumi)".
[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Annabi -kí ikẹ Ọlọhun àti ọlá Rẹ o máa ba a- ṣe alaye pé eewọ ni lati ta ẹjẹ musulumi silẹ, àyàfi tí o ba ṣe ọkan nínú awọn nkan mẹta (wọnyi): Alakọkọ: ẹni tí o ba ṣe àgbèrè (zina), tí o si jasi pe o ti ṣe ìgbeyàwó l'ọna tí o lalaafia, nigbanaa o tọ kí a o sọ l'oko pa (titi ti ẹmi o fi bọ lara rẹ). Ẹlẹẹkeji: ẹnikẹni ti o ba maama pa ẹmi kan (ti a se l'eewọ lati pa) laisi ẹtọ, a o pa oun naa di pẹlu awọn majẹmu (ati ofin) ti o ro papọ mọ. Ẹlẹkẹta: ẹni tí o ba yapa kúrò láàrin awujọ awọn musulumi, bóyá nipa fífi ẹṣin Islam silẹ nipasẹ (Ridda), tabi ẹni tí o nya pá l'ọtọ lai ṣe (Ridda) nipasẹ fífi apakan (ofin Islam) silẹ, gẹgẹ bi awọn obilẹjẹ ènìyàn, àti awọn adigun jàle, ati awọn olujagun nínú àwọn Khawaarij àti awọn miran.

https://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/4714

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee